# OFIN JẸ́ OLUKỌNI

### Galatia 3:1-29

### ẸKỌ 398 – FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Ṣugbọn olododo ni yio yè nipa igbagbọ́: ṣugbọn bi o ba fà sẹhin, ọkàn mi kò ni inu didùn si i" (Heberu 10:38).**

**Ododo nipa Igbagbọ́**

"Olododo ni yio yè nipa igbagbọ́" jẹ́ ofin Ọlọrun ti o ti wà lati ayebaye. Kaini ati Abẹli ni awọn ẹni kin-in-ni ti a kọ́ bi si inu ayé yii, "nipa igbagbọ́" si ni "Abẹli ru ẹbọ si Ọlọrun ti o san ju ti Kaini lọ, nipa eyiti a jẹri rẹ̀ pe olododo ni" (Heberu 11:4). Lati jẹ́ olododo ni lati bọ́ lọwọ ẹ̀ṣẹ. Igbagbọ Abẹli ni o sọ ọ di olododo, ti o si mu ki ẹ̀bun rẹ̀ ṣe itẹwọgba. Kaini kún fun ẹ̀ṣẹ kò si ni igbagbọ́, nitori naa ẹ̀bun rẹ̀ kò si jẹ́ itẹwọgba. Iṣẹ rere ti awọn eniyan n ṣe kò le yi ọkàn wọn pada, ki o si sọ wọn di Onigbagbọ tootọ. "Nitori ore-ọfẹ li a ti fi gbà nyin là nipa igbagbọ́; ati eyini ki iṣe ti ẹnyin tikaranyin: ẹ̀bun Ọlọrun ni: ki iṣe nipa iṣẹ, ki ẹnikẹni má bã ṣogo" (Efesu 2:8, 9).

Nigba ti a ba ti sọ eniyan ti olododo nipa igbagbọ́, oun yoo maa ṣiṣẹ rere. Ṣugbọn Ọlọrun ki yoo gba iṣẹ awọn alaiṣododo. O dun Kaini nitori pe ẹbọ rẹ̀ kò jẹ́ itẹwọgba, ṣugbọn Ọlọrun wi fun un pe: "Bi iwọ ba ṣe rere, ara ki yio ha yá ọ? Bi iwọ kò ba si ṣe rere, ẹ̀ṣẹ ba li ẹnu-ọ̀na" (Gẹnẹsisi 4:7).

**Baba Igbagbọ́**

A mọ Abrahamu gẹgẹ bi Baba awọn oloootọ. Oun ni ipilẹṣẹ iran awọn Ju; nigba ti Jesu wà ni ayé, ti awọn Ju kò gba iwaasu Rẹ̀ gbọ́, wọn a maa wi pe "Abrahamu ni baba wa" (Johannu 8:39). Ṣugbọn Jesu wi fun wọn pe Abrahamu ti ni igbagbọ́, o si ti gba Jesu gbọ́ ṣaaju ki a to bi Jesu. "Abrahamu baba nyin yọ̀ lati ri ọjọ mi: o si ri i, o si yọ̀" (Johannu 8:56). A gba Abrahamu là nipa igbagbọ rẹ̀ ninu Jesu, o si mu inu rẹ̀ dùn.

Abrahamu n gbé laaarin awọn abọriṣa ṣugbọn o feti silẹ nigba ti Ọlọrun pe e, o si gbọran si ipe naa. Abrahamu "gba OLUWA gbọ́; on si kà a si fun u li ododo" (Gẹnẹsisi 15:6). Awọn iṣẹ rere ti Abrahamu ṣe ni gbogbo iyoku igbesi ayé rẹ̀ fi hàn pe igbagbọ rẹ̀ ni o gba a kuro ninu ẹ̀ṣẹ.

Nitori pe Abrahamu gbagbọ́, o si gbọran si Ọlọrun lẹnu, Ọlọrun ṣe ileri fun un pe, "Ninu rẹ li a o ti bukun fun gbogbo idile aiye" (Gẹnẹsisi 12:3). Lati inu iran Abrahamu ni a o ti bi Jesu, ati nipa Jesu ni igbala yoo di ọfẹ fun gbogbo orilẹ-ède agbaye. Ofin ti a fun ni ni Oke Sinai ni irinwo ọdun o le ọgbọn lẹyin eyi kò yẹ ileri ti Ọlọrun fi fun Abrahamu.

**Ihin Ayọ̀**

Itumọ Ihinrere ni "ihin ayọ, ni pataki ihin ayọ̀ nipa Kristi, Ijọba Ọlọrun ati Igbala." (Gẹgẹ bi atumọ ọ̀rọ lati ọwọ Webstar). Ninu ẹ̀kọ wa oni Paulu Apọsteli sọ bayii pe: "Bi iwe-mimọ́ si ti ri i tẹlẹ pe, Ọlọrun yio dá awọn Keferi lare nipa igbagbọ́, o ti wasu ihinrere ṣaju fun Abrahamu, o nwipe, Ninu rẹ li a o ti bukún fun gbogbo orilẹ-ède." Eyi jẹ́ ẹri pe awọn eniyan ti o wà nigba Majẹmu Laelae ri igbala gbà nipa igbagbọ́, gẹgẹ bi awa pẹlu ti n ri i gbà lọjọ oni. A waasu Ihinrere fun wọn nipa ileri pe Jesu yoo mu igbala wá fun gbogbo eniyan. Eredi rẹ̀ ti ọ̀rọ naa kò fi ṣe awọn ti o gbọ́ ọ ni rere ni pe wọn kò ni igbagbọ́ ninu ọrọ naa (Heberu 4:2).

Nipa iwaasu Ihinrere ni a fi gba awọn ara Galatia là. Inu wọn dùn pupọ nigba ti wọn ri idariji ẹ̀ṣẹ wọn gbà, ti wọn si mọ̀ pe awọn ti di Onigbagbọ. Ṣugbọn lai pẹ wọn bẹrẹsi ronu nipa ilana ati eto isin ti wọn ti n ṣe tẹlẹ ri labẹ Ofin, wọn rò pe awọn gbọdọ maa ṣe awọn diẹ ninu wọn pẹlu. Nitori eyi, Paulu pe wọn ni "alaironu ara Galatia."

**Bẹrẹ ninu Ẹmi**

**Nigba naa ni Paulu fi ibeere yii siwaju wọn; "Nipa iṣẹ ofin li ẹnyin gbà Ẹmi bi, tabi nipa igbọran igbagbọ́?" Ki a sọ ọ ni ọna miiran: Njẹ nipa pipa ofin mọ́ ni a fi gbà wọn là tabi nipa igbagbọ́ ninu Jesu? A ti sọ wọn di olododo nipa igbagbọ́ wọn ninu Jesu ati nipa pipa ofin Rẹ̀ mọ́.**

**O rán wọn leti pe, olododo yoo yè nipa igbagbọ́, ati pe lọna bayii ni wọn ṣe bẹrẹ ire-ije igbagbọ́ wọn. Wọn ti fara da ọpọ inunibini nitori igbagbọ́ wọn ninu Jesu. Njẹ lasan ni wọn jẹ gbogbo iya yii bi? Wọn ha n fẹ tẹ́ awọn Ju lọrun nisisiyii nipa iṣẹ Ofin?**

**Nigba ti a ba tun wa bi "Ẹmi tikararẹ̀ li o mba ẹmi wa jẹri pe, ọmọ Ọlọrun li awa iṣe" (Romu 8:17). Nipa bayii awa ti "bẹ̀rẹ ninu Ẹmi." Ẹmi jẹri si i nigba ti awa gbagbọ, ki i si iṣe nitori iṣẹ rere kan ti awa ṣe. Lati igba naa lọ, a ni lati rin nipa igbagbọ́, "Nitoripe nipa igbagbọ́ li awa nrin, ki iṣe nipa riri" (2 Kọrinti 5:7).**

**Nipa igbagbọ awa pẹlu le jẹ ọmọ Abrahamu, ki a si jogun awọn ibukun ti Ọlọrun ṣeleri fun Abrahamu. "Ki iṣe eyiti o farahan ni Ju,…… ṣugbọn Ju ti inu ni Ju, ati ikọla ti ọkàn, ninu ẹmi ni, ki iṣe ti ode ara" (Romu 2:28, 29). Nitori naa bi awa ba ni igbagbọ́ ninu Jesu gẹgẹ bi ti Abrahamu, awa jẹ́ ọmọ Abrahamu ati ajogun ileri iye ainipẹkun.**

**O wà ninu Ofin pe: "Ifibu ni olukuluku ẹniti kò duro ninu ohun gbogbo ti a kọ sinu iwe ofin lati mã ṣe wọn." Awọn eniyan ti o wi pe awọn le ri igbala nipa pipa Ofin mọ n sọ ju ohun ti wọn le ṣe. Lai si Ẹmi Ọlọrun ninu ọkàn ó ṣoro lati pa Ofin mọ́ eyi ti o jẹ apa kan ninu Ofin Mẹwaa.**

**Eredi ti a fi fun ni ni Ofin**

Bi o ba ṣoro lati pa gbogbo Ofin mọ bi ko ṣe pe a ba dá wa lare nipa igbagbọ; bi a ba si le dá Abrahamu lare nipa igbagbọ ṣiwaju fifun ni ni Ofin, ki ni ṣe ti a tun ni lati fi Ofin fun ni? Paulu wi bayii pe: "A fi kun u nitori irekọja titi irú-ọmọ [Jesu] ti a ti ṣe ileri fun yio fi de" Ọlọrun le bá Abrahamu sọrọ nitori pe ọkàn rẹ̀ rọ̀; ṣugbọn iru eniyan bi rẹ̀ ṣọwọn. Abrahamu le ri i pe Jesu n bọ̀, ṣugbọn ọpọlọpọ eniyan ni wọn ti dá ẹ̀ṣẹ pupọ to bẹẹ ti ẹri-ọkàn wọn ti sébọ ti wọn ko tun le gbọ́ ohùn Ọlọrun. Wọn kò ni igbagbọ́, nitori naa Ọlọrun fun wọn ni isin ti wọn le ri, awọn Ju nikan ni a si fi i fun ni pataki.

Ofin paṣẹ fun awọn Ọmọ Israẹli lati mú ẹran wá sinu Agọ fun irubọ si Ọlọrun. Nipa igbagbọ ni awa n mu ọkàn wa ati ifẹ ọkàn wá lati fi fun Ọlọrun. Onipsalmu wi bayii pe "Ẹbọ Ọlọrun ni irobinujẹ ọkàn: irobinujẹ ati irora aiya, Ọlọrun, on ni iwọ ki yio gàn" (Orin Dafidi 51:17). A ko le fi oju wa ri "irobinujẹ ọkàn" ṣugbọn a le mọ ọn lara nigba ti eniyan kan ba ni ibinujẹ nitori awọn ẹ̀ṣẹ rẹ̀ ti o si n fẹ ki Oluwa ki o dariji oun.

Ohun pupọ ninu Ofin Majẹmu Laelae ni o jẹ́ aworan otitọ Majẹmu Titun. Gbogbo awọn ẹran ti a fi n rubọ labẹ Ofin n tọka si bi Jesu yoo ti wá lati kú fun ẹ̀ṣẹ wa ti yoo ta Ẹjẹ Rẹ̀ silẹ lori Agbelebu ti Kalfari lati ṣe etutu fun awọn eniyan.

Apa kan ninu Ofin ni Agọ ati eto isin ti Agọ. Ni Ibi Mimọ ni pẹpẹ turari nibi ti oorun didun ti n lọ sọdọ Ọlọrun nigba gbogbo. Nigba ti a ba ni isọdimimọ patapata, iyin yoo maa lọ sọdọ Ọlọrun lati inu ọkàn wa lati igba de igba gẹgẹ bi "õrùn didùn ni, ẹbọ ti a fi iná ṣe si OLUWA" (Ẹksodu 29:18). Ọpa fitila wura ni o n tan imọlẹ si Agọ naa. Jesu wi pe, "Emi ni imọlẹ aiye" (Johannu 8:12). Tabili akara ifihan pẹlu, n tọka si Jesu gẹgẹ bi Onjẹ Iye (Johannu 6:35). Ohun gbogbo ni o n tọka si Jesu. Oun nikan ni o le gbà wọn là kuro ninu ẹ̀ṣẹ wọn.

**Olukọni**

Ofin jẹ olukọni ti n kọ́ ni lẹkọọ nipa Jesu. Iṣẹ olukọni ni lati kọ́ awọn ọmọ ile-ẹkọ rẹ̀. Nigba ti Jesu ti wá si aye, a ko tun fẹ olukọ tabi "olukọni" mọ́.

Iṣoro ti o wa fun awọn Ju ni pe kaka ki wọn wo Jesu ti Ofin n tọka si, wọn n wo "ohun ti n tọka." Wọn kò le ri Jesu ninu gbogbo ẹbọ wọn nitori aigbagbọ. Oku ẹran nikan ni wọn n ri. Eredi rẹ̀ ni eyi ti inu Ọlọrun ko fi dùn rara si wọn ni igba aye Wolii Isaiah ti O si wi pe: "OLUWA ni, kini ọ̀pọlọpọ ẹbọ nyin jasi fun mi? emi kún fun ọrẹ sisun agbò, ati fun ọrá ẹran abọ́pa; bẽni emi kò si ni inu didùn si ẹjẹ akọ malũ, tabi si ti ọdọ-agutan, tabi si ti obúkọ. Ẹ má mu ọrẹ asan wá mọ́: turari jasi ohun irira fun mi; oṣù titun ati ọjọ isimi, ipe ajọ, emi kò le rọju gbà; ẹ̀ṣẹ ni, ani apẹ̀jọ ọ̀wọ ni" (Isaiah 1:11, 13). Ọlọrun ni o ṣe ilana gbogbo ẹbọ wọnyii ninu Ofin; ṣugbọn nigba ti awọn eniyan ko ni igbagbọ to lati ri Jesu ninu

wọn, awọn ẹbọ wọnyii kò mu ire wá, o si sú Ọlọrun lati gbà wọn. Ọlọrun wi fun awọn Ọmọ Israẹli pe Oun ki yoo gbọ́ adura wọn.

**Alarina**

Paulu Apọsteli tun wi pẹlu pe, “A si ti ipasẹ awọn angẹli ṣe ilana rẹ̀ lati ọwọ́ alarina kan wá”. Mose ni alarina naa, tabi ẹni ti o wà laaarin. O sọ nipa ti Ọlọrun fun awọn eniyan, o si n mu iṣoro awọn eniyan tọ Ọlọrun lọ. Gẹgẹ bi alarina, Mose pẹlu dabi Kristi. Mose wi pe, “OLUWA Ọlọrun rẹ yio gbé wolĩ kan dide fun ọ lãrin rẹ, ninu awọn arakunrin rẹ, bi emi; on ni ki ẹnyin ki o fetisi” (Deuteronomi 18:15). O n sọrọ nipa Kristi ti yoo lọ si Ọrun lati bẹbẹ fun wa, gẹgẹ bi alufaa ti n ṣe. Oun jẹ́ Aṣoju wa niwaju Ọlọrun; nitori O ta Ẹjẹ Rẹ̀ silẹ fun wa, a ni ẹtọ lati fi igboya wá siwaju Ọlọrun, lai bẹru ibinu Rẹ̀. Nigba ti Ẹjẹ Jesu ba ti wẹ ẹ̀ṣẹ wa nù ti o si ti sọ wa di mimọ laulau ninu ọkàn, awa ni “igboiya lati wọ̀ inu ibi mimọ́ nipasẹ ẹ̀jẹ Jesu” (Heberu 10:19).

Nipa bayii, a le ri i pe ninu gbogbo Majẹmu Laelae, Ọlọrun n fun wa ni apẹẹrẹ Jesu ati ti igbala ti Oun yoo mu wá. Yoo jẹ́ igbala nipa igbagbọ́; awọn ti igba Majẹmu Laelae ti o ni igbagbọ ri igbala gbà gẹgẹ bi awa naa ti n ri i gbà. Olododo yoo maa yè nipa igbagbọ́ titi Jesu yoo fi de ti igbagbọ yoo si fi di afojuri.

## AWỌN IBEERE

1 Ki ni ṣe ti ẹbọ Abẹli fi jẹ́ itẹwọgba, ṣugbọn ti Ọlọrun kọ ti Kaini?

2 Ta ni Baba awọn olododo?

3 Ki ni ileri ti Ọlọrun ṣe fun un?

4 Ki ni itumọ “Ihinrere”?

5 Ki ni ṣe ti Paulu fi pe awọn ara Galatia ni alaironu?

6 Bawo ni a ṣe n mọ̀ bi a ba ri igbala?

7 Ki ni ṣe ti a fi Ofin fun ni? Ta ni a fi i fun?

8 Ki ni fifi ẹran rubọ tọka si?

9 Sọ awọn ọ̀na ti Agọ fi n tọka si Jesu?

10 Bawo ni awọn olododo yoo ṣe yè?